# MOSE BẸRẸ IṢẸ́ RẸ̀

**Ẹksodu 4:1-23, 27-31**

**ẸKỌ 49 --- FUN AGBA**

**AKỌSORI: "Tali o dá ẹnu enia? tabi tali o dá odi, tabi aditi, tabi ariran, tabi afọju? Emi OLUWA ha kọ́?" (Ẹksodu 4:11).**

**I Awọn Ami lati mu ki Israẹli Mọ Iṣẹ́ ati Aṣẹ ti a fi le Mose Lọwọ**

1 Mose rò pe Israẹli ki yoo gbagbọ́ pe Ọlọrun ni o rán oun, Ẹksodu 4:1; Matteu 13:57

2 Ọpa Mose di ọpa Ọlọrun, ami lati fi agbara Ọlọrun hàn fun Israẹli, Ẹksodu 4:2-5, 20; 14:16; 17:5-7, 9-12; Awọn Onidajọ 6:36-40; 2 Awọn Ọba 20:8-11

3 Ami keji fi agbara Ọlọrun hàn lori gbogbo eniyan ati pẹlu lori ohun gbogbo ti kò ni ẹmi, Ẹksodu 4:6-8

4 Ami kẹta, omi ti o di ẹ̀jẹ, fi agbara Ọlọrun lori ẹ̀dá hàn, Ẹksodu 4:9

**II Àwawi Mose ati Iranwọ Ọlọrun**

1 Mose sọ awọn ailera rẹ̀ nipa ti ara fun Ọlọrun, Ẹksodu 4:10; Awọn Onidajọ 6:15; 1 Samuẹli 9:21; Jeremiah 1:6-10

2 A rán Mose leti pe Ọlọrun ni Ẹlẹda eniyan, a si tun aṣẹ naa fi fun un, Ẹksodu 4:11, 12; 1 Kronika 29:12

3 Mose tún ṣe àwawi si i, Ẹksodu 4:13

4 Ọlọrun bínú si Mose, ṣugbọn O yan Aarọni arakunrin rẹ̀ fun un, lati ran ailera rẹ̀ lọwọ, Ẹksodu 4:14-17

**III Ipadabọ Mose si Egipti**

1 Mose gba ìpè naa, o si gba àyè lati fi iṣẹ́ rẹ̀ atẹyinwa silẹ, Ẹksodu 4:18-20; 1 Awọn Ọba 19:19-21

2 Ọlọrun sọ fun Mose tẹlẹ nipa kikọ̀ ti Farao yoo kọ̀, Ẹksodu 4:21; Isaiah 46:9, 10; 6:9, 10; Matteu 13:14, 15

3 "Ọmọ mi ni Israẹli, … akọ́bi mi," Ẹksodu 4:22, 23; Gẹnẹsisi 25:23; Orin Dafidi 33:12; 1 Kronika 16:13; Deuteronomi 14:2; Romu 3:2

4 Ni igbọran si aṣẹ Ọlọrun, Aarọni pade Mose lori oke Ọlọrun, Ẹksodu 4:27, 28

5 Iṣẹ́ ti Ọlọrun rán ati awọn àmi naa fi han Israẹli pe a ti gbọ́ imi-ẹdùn ati igbe wọn, Ẹksodu 4:29-31; 2:23-25; 3:7, 8

## ALAYE

Igbesi-ayé Mose lati ibẹrẹ jẹ imúrasilẹ fun iṣẹ ti a ti yàn silẹ fun un ninu eto nla Ọlọrun fun Israẹli ati gbogbo ayé. Oun ni yoo jẹ́ alakoso ogunlọgọ awọn eniyan ti wọn ko i ti ni eto iṣakoso ri, yoo si ṣe alarina laaarin awọn ati Ọlọrun, lati fi ifẹ Ọlọrun hàn wọn. Lati inu igbẹ ti n jó ni Ọlọrun ti sọ fun Mose ni kukuru, nnkan ti Oun yoo ṣe si awọn ara Egipti ati fun awọn Ọmọ Israẹli lẹyin isinrú wọn ni Egipti. O si sọ fun Mose lati mú eto Rẹ̀ wọnyii ṣẹ.

O daju pe Mose ri awọn iṣoro ti o wà niwaju rẹ̀ ti o ni lati bori. Ọlọrun sọ fun un pe ki o sọ Ẹni ti o rán an niṣẹ fun awọn Ọmọ Israẹli, Mose si beere awọn ami ti yoo mu ki ọkẹ aimoye awọn Ọmọ Israẹli wọnyii mọ̀ pe otitọ ni ipè oun ati pe Ọlọrun ni o fun oun ni aṣẹ.

Boya, pẹlu ifihan wọnyii paapaa, Mose kò ni òye tó nipa awọn iṣẹ-iyanu ti Ọlọrun yoo ṣe fun igbala Israẹli. O ti ri ọwọ́ Ọlọrun ninu iṣẹ-iyanu ti igbẹ ti n jó, lati ibi ti Ọlọrun ti ba a sọ̀rọ. O ti ri ọwọ́ oun tikara rẹ ti o funfun bi ojo didi nigba ti ẹ̀tẹ bo o, ti a si tun wo o sàn lẹyin naa. O ri ọpa ti o di ejo ti o si tun pada di ọpa, nigba ti o di i mu ni igbọran si aṣẹ Ọlọrun.

Lai si aniani, ọpa oluṣọ-agutan lasan ni ọpa yii, iru eyi ti olukuluku oluṣọ-agutan maa n mú lọwọ ni akoko ti oun nikan ṣoṣo ba n ṣọ́ agbo-ẹran rẹ̀ fun ọpọlọpọ wakati -- ṣugbọn wo iru itan iyanu ti a o gbọ́ nipa ọpa yii! Oun ni a o nà si Okun Pupa lati tọka ọna laaarin ibú omi já. Oun kan naa ni a o si fi lu okutan ibọn, ni ọjọ iwaju, ti a o si mú omi jade lati pa ongbẹ ogunlọgọ eniyan, ti yoo si gbà wọn lọwọ ikú. Oun ni a o gbé soke fun iṣẹgun lori Amaleki. Oun naa ni a o tún maa pe ni ọpa Ọlọrun!

Nigba ti Ọlọrun ba n fẹ ohun-elo fun iṣẹ Rẹ̀ -- i baa ṣe nnkan ti kò ni ẹmi tabi eniyan kan – Oun ki i saba yan ọpa wura tabi ọjọgbọn eniyan. Dipo eyi, ni ọpọlọpọ igbà, Oun a lo ohun alailera ati eyi ti kò ni laari lati fi daamu awọn ọlọgbọn ati awọn alagbara, ki awọn eniyan ba le fi ogo fun Ẹlẹda wọn ju ọgbọn-ori wọn ati ohun ti wọn ṣe (1 Kọrinti 1:27-29). Ọpa ni Ọlọrun lò ni akoko yii. Nigba miiran O lo iwo ẹran, akara ọkà barle, pari-ẹrẹkẹ

kẹtẹkẹtẹ, iṣa amọ, kanna-kanna oluṣọ-agutan kan, Gideoni ọdọmọkunrin kan, Saulu ti o n fi ara rẹ pamọ́, Dafidi oluṣọ-agutan kekere kan, Isaiah ati Jeremiah ti wọn ri ara wọn bi alaiyẹ ati Johannu Baptisti onirẹlẹ eniyan. "Ọpa" kan ti Ọlọrun ba tì lẹyin lagbara pupọ ju ẹgbẹ ọmọ-ogun nla lọ; ọkunrin kan ti Ọlọrun ba wà pẹlu rẹ san ju ẹgbẹrun ti kò ni Ọlọrun lọ (Deuteronomi 32:30; Jọṣua 23:10).

Iṣẹ-iyanu jẹ ohun ti agbara Ọlọrun n ṣe, ti kò si fara kọ́ ohun ti a n pe ni ofin ẹda, ṣugbọn ti o n jẹri si aṣẹ ti ẹni kan ni tabi otitọ ẹkọ kan. Igbẹ ti n jó jẹ iṣẹ-iyanu niwọn bi iná ti kò jo igbẹ́ run ti lodi si ofin ẹda. Bakan naa ni sisọ ọpa di ejo ati ọwọ́ ti ẹ̀tẹ̀ bò, ti o sàn ti o si pada bọ̀ sipo. Ko si agbara ẹda kan ti o le ṣe nnkan wọnyii, nitori agbara naa kọja ofin ẹda, ṣugbọn agbara lati oke wá ni o le ṣe wọ́n.

O gba Mose ni igbagbọ́ bi ti ọmọ kekere ati igbọran lati sọ ọpa rẹ̀ silẹ lai mọ ipinnu Ọlọrun; ṣugbọn igbagbọ́ nla gidigidi ati igbẹkẹle ninu Ọlọrun ni o gba Mose lati di ejo naa mú, eyi ti oun ti fi ibẹru sá fún. Igbagbọ́ bi ti ọmọ kekere ati ifọkantan ni o tun mu un gbọran si Ọlọrun lati fi ọwọ́ rẹ̀ si aya rẹ̀ ki o si ri pe oun fa a jade pẹlu ẹ̀tẹ̀, ti o si n rùn; o si gba igbagbọ́ nla lati da a pada ki o si mọ agbara iwosan ti o wẹ ẹ mọ́ ti o si tun ṣe e bi ẹya ara rẹ̀ iyoku.

A dán igbọran Mose paapaa wò, nitori bi a ti n fi iṣẹ rẹ hàn an, ti a si n jẹ ki o ye e ni o n bẹ̀ru titobi iṣẹ naa. O mọ pataki iṣẹ Ọlọrun, ati ainilaari ti rẹ̀, ati ẹrù wuwo ti yoo jẹ ti rẹ bi o ba gba iṣẹ naa. Bi a ba fi oju wo o gẹgẹ bi ẹda, ta ni le ba Mose wi fun ibẹru rẹ?

Ọlọrun rán Mose leti pe o ni lati gbẹkẹle Ẹlẹda rẹ̀ ni akoko aini; nipa awawi rẹ siwaju si i, Mose fa ibinu Ọlọrun, eyi ti o fi hàn pe ki i ṣe iwa pẹlẹ ati irẹlẹ Mose nikan ni o mu un fa sẹyin. Titobi iṣẹ naa ati kikọ̀ ti o fẹrẹ daju pe Farao yoo kọ̀ ẹbẹ̀ ti a sọ fun Mose lati bẹ̀, ni o mu ki Mose má fẹ́ ẹ gbe ẹru naa. Ṣugbọn lẹẹkan si i Ọlọrun tun fi suurù ati aanu ti O fi n bá awọn eniyan lo hàn. O sọ fun Mose pe Aarọni yoo ba a lọ yoo si maa ṣe ẹnu fun un.

Eto titun yii fi opin si awawi Mose pe oun kò tó duro ni agbala ọba ki oun si lagbara lati maa bẹ̀bẹ̀ fun awọn Ọmọ Israẹli ti a n jẹ niya, sibẹ eyi kò gbe ẹrù yii kuro lori rẹ. Aarọni ni yoo jẹ ẹnu, ṣugbọn Mose ni yoo jẹ ikọ̀ sibẹ laaarin Ọlọrun ati Israẹli -- ẹni ti yoo maa sọ ifẹ inu Ọlọrun bi ọran ba delẹ. Ẹkọ nipa igbesi-ayé ọkunrin oloootọ yii fi hàn bi o ti ṣe iṣẹ daradara to. O tobi to bẹẹ gẹẹ, o si ṣọwọn fun awọn eniyan to bẹẹ ti awọn Ọmọ Israẹli fi sọkun fun ọgbọ̀n ọjọ nigba ti o kú. Nipa imisi Ọlọrun, Iwe Mimọ́ sọ fun ni pe wolii kan kò si hù mọ ni Israẹli bi Mose "ẹniti OLUWA mọ̀ li ojukoju" (Deuteronomi 34:10-12).

Igbesi-ayé Mose jẹ ifihan ohun ti Ọlọrun le fi ẹni ti o bá yọọda aye rẹ ṣe. Mose gbà pe oun ko mọ̀ ọrọ i sọ; sibẹ, ninu Deuteronomi 32:1, o pe ọrun on ayé lati tẹti silẹ si i! Ẹni ti o ba si kà awọn ohun wọnni ti o sọ silẹ fun awọn Ọmọ Israẹli paapaa, yoo ri i pe ahọn rẹ ti o kólòlò ko di i lọwọ. O rọrun lati mọ̀ aṣiiri yii. Bi o tilẹ jẹ pe oun jẹ akólòlò gẹgẹ bi ẹda, sibẹ nigba ti o ba n ṣiṣẹ fun Ọlọrun labẹ imisi Ẹmi Mimọ́, a o ri i pe o di ẹni ti "o si pọ̀ li ọ̀rọ ati ni iṣe" (Iṣe Awọn Apọsteli 7:22).

Loju kan naa ti Mose gbà aṣẹ lati ọdọ Ọlọrun, o kọja lọ si Egipti lẹsẹkẹsẹ, lai sọ fun Jetro nipa titobi iṣẹ ti a ran an. O huwa ọlọgbọ́n nihin yii bi o ti pa ọrọ naa mọ́. Boya ni akoko ti o n lọ si Egipti ni o fi aya ati awọn ọmọ rẹ̀ ranṣẹ si Jetro, baba aya rẹ, nitori ko dá ni loju pe wọn wa pẹlu rẹ ni Egipti, niwọn bi a ti ri i pe wọn tun jọ ba ara wọn pade lẹyin ijade kuro ni Egipti (Ẹksodu 18:2-6).

Bawo ni Ọlọrun ti ṣe ohun gbogbo lọna iyanu to! O bá Aarọni ti o wà ni Egipti sọ̀rọ̀, O si wi fun un pe ki o lọ pade Mose. Ori Oke Ọlọrun ni wọn ti pade – nibi ti Ọlọrun ti ba Mose sọrọ-- nibẹ si ni awọn arakunrin mejeeji yii ti baa ara wọn sọrọ. Mose sọ aṣẹ ati èto Ọlọrun fun Aarọni, nipa eyi ti o mú ọrọ Ọlọrun ṣẹ pe Mose wà bi ọlọrun fun Aarọni.

Wọn lọ si Egipti, wọn si lọ bá awọn agbà Israẹli, wọn si ṣe awọn iṣẹ-iyanu naa niwaju awon Ọmọ Israẹli. "Awọn enia na si gbagbọ́" wọn si sin Ọlọrun, nitori O ti gbọ́ igbe ati gbigbin wọn, ti O si rán idasilẹ yii si wọn ni akoko aini wọn.

## AWỌN IBEERE

1 Ki ni ami mẹta ti Ọlọrun fun Mose lati fi hàn awọn Ọmọ Israẹli?
2 Sọ awọn akoko ti a lo ọpa Mose.
3 Ki ni ṣe ti Mose bẹ̀ru lati ṣe alakoso Israẹli?
4 Ihà wo ni Ọlọrun kọ si ibẹru Mose?
5 Ki ni Ọlọrun gbà lati ṣe fun Mose?
6 Ki ni Ọlọrun sọ fun Mose pe ki o maa reti lati ọdọ Farao?
7 Ki ni Ọlọrun pe Israẹli ni akoko yii?
8 Bawo ni Aarọni ṣe mọ ibi ti oun yoo gbe lọ pade Mose?
9 Ki ni ojuṣe ti Aarọni ni i ṣe nigba ti wọn ba fara hàn niwaju Farao?
10 Nigba ti awọn Ọmọ Israẹli ri ami wọnyii, ki ni wọn ṣe?